ASỌJẸ ORO

Olore ko ni ku, olo
ore o ni run, gba
olore ko ni fọ, awo
olore no ni nu, aiṣpa
aole aiṣpaole kuọ
kulọ, kulọ ore, towo
ọme lo nyale olore.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJO

OWE YORUBA

Yibiti a ngefufu lẹle
edari igbẹ si, ibiti o
a wo olowo ẹni lo
itan ni lọ. Afẹfẹ lo
se ori igi yẹriyeri ẹfu
a lo si nte ori agbon
roko. Ala ko ngb
gbo olore. Agutan ko
gbagbe eleti boro.

VOL. XII No. 666. LAGOS, SATURDAY, MARCH 12, — MARCH 18, 196. KỌBỌ MEJI (2d)

# Oloye Akintola Pagbo Se'be Oyinmomo!

**Oloye S. L. Aknitola ṣe ipade kanpapo pelu awon oniwe irohin, o si ba won soro nipa owo ori, eyiti o ti nfe da edekoyede sile ni agbegbe Iwo-orun Imoran, na titun ti Oloye Akintola gba nipa owo ori fun gbogbo awon obinrin ti o wa ni Iwo orun, ati awon ti ko si lenu ise rara niwonyi:**

Oloye na sọ wipe iru ọna ti Ijọba Iwọ orun ti ngba iati ma fi gba owo ori lọwọ awọn enia ko dara to, o si yẹ ki a pa rẹ. Dipo owo ori, awọn enia yio ma sanwo ọdọdun, awọn igbimọ ilu kọkan ni yio si ma gba owo ilu wọn.



OLOTU IJỌBA IWỌ-ORUN

Owo ọdọdun ti ao ma san ni ipinlẹ Iwọ Orun, yio je iye kanna, nain (9d) pere lori Ponun kan. Gbogbo awon obinrin ti o ngbe ipinlẹ Iwọ Orun ilẹ Nigeria, ko ni san owo ori mọ, nwon ko si ni san owo ina tabi owo omi mọ.

Nipa owo ọdọdun ti awon enia yio ma san, Ijọba yio da ẹgbẹ kan silẹ ti ao ma pe ni Area Assesment Committee. Oloye Akintola sọ fun awọn oniwe irohin ọrọ ti wipẹ ki awon obinrin ma san owo ori mọ ti wa ninu ero ijọba siwaju ki on to de ipo Premier Oloye Awolọwọ lo si yẹ ka fi ọpẹ na fun nitori ti ko lowo ilu ni ilekulo.

OWO ORI WỌLE FUN OBINRIN. E DIBO FUN ỌPE. IGI OWO

Irohin ko afoluba ni agbe- Iwọ Orun, nigbati Oloye Akintọla sọ wipe awọn obinrin ko ni sanwo ori owo ina ati owọ omi mọ, ibosi ẹ dibo fun ọpẹ, ọpẹ ti wọle, logbojiyan kakiri ilu.

Nigboro Abẹokuta, Sir Ademola Alake Ọba Abẹokuta sọ ninu ofin rẹ wipe bi enia ba gun esi ninu on gerrge ni yio lọ lati fi han gbangbi ina on ti dun to nigbati on gbọ pe ijọba yọ awọn obinrin kuro patapata ninu awọn ti yio ma san owo ori.

Alaiyeluwa Ọṣilẹ Oke Ọna sọ wipe irohin to gbadun ni eyiti mo gbọ lakoko ti mo mbẹ lori ekun adura ni wipe awon obinrin ilẹ Yoruba ko ni sanwo ori, owo omi, ati owo ina mọ.

## OMOBA MARGARET FE SE IGBEY. .WO.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni ọmọba Margeret, aburo lẹhin Ọba ilu Gẹsi, ọmọ iya ati ọmọ baba kan-na ni awọn mejeji, ninu oṣu May 1960 ni nwọn o gbe ni iyawo nigboro Loudon.



# Ijebu-Ode Railway Out-Agency

In order to facilitates the receipt despatch of traffic a railway Out-Agency has been open at Ijebu Ode.

Freight traffic will be accepted at the Railway Out-Agency for despatch to any Station on the Nigeria Railway : and similarly traffic may be sent from any railway station in Nigeria to the Ijebu-Ode Out-Agency for delivery'.

HOURS OF SERVICE ARE

| | | |
|---|---|---|
| MONDAYS — FRIDAYS | | 07.00 Hrs to 12.00 Hrs |
| | — — | 14·00 Hrs to 16.00 Hrs |
| SATURDAYS | — — | 07 00 Hrs to 12.00 Hrs |

and at other times by special request.

The freights rates are the same as those in operation to and from Ibadan station plus 20/- per ton the cartage between Ibadan and Ijebu — Ode.

EXAMPLES OF THESE RATES ARE :

| COMMODITY | TO OR FROM | Inclusive rate per ton from or to Ijebu-Ode Out-Agency |
|---|---|---|
| GARI | Kano | 93s |
| " | Ilorin | 34s |
| " | Minna | 65s |
| " | Gusau | 95s |
| KOLANUT | Gusau | 182s |
| " | Kano | 180s |
| " | Malam Maduri | 190s |
| " | Sokoto | 201s |
| PALM OIL | Kano | 164s |
| " | Zaria | 155s |
| " | Ilorin | 75s |
| " | Jebba | 99s |
| SHEA BUTTER | Minna | 115s |
| " | Badeggi | 123s |
| BEANS | Kano | 91s |
| RICE | Gusau | 92s |
| RICE | Zaria | 84s |
| DRIED MEET | Nguru | 145s |
| " | Kano | 133s |

Enquiries are invited concering this Out-Agency, and the facilitiatis available:

PHONE 44399 or write to:-

**District Superintendent**
Nigeria Railway Corporation
Ebute Metta Junction


# E Ma Ka

# Iwe Irohin Eleti-Ofe

# L'osose

## Nwon Da Seriya Fun Awon Omo Akeko Ti o Dite

IKARE. Agbọ irohin wipe awọn ọmọ akẹkọ ti o mbẹ ni ile ẹkọ Victoria College nilu Ikarẹ enia mẹtalelọgorun ninu wọn lo ditẹ si Alabojuto wọn sugbọn awọn merinlelọgbọn ti awọn se alya gbangba larin wọn ni nwọn le kuro ninu ile ẹkọ na lẹhin ti awọn igbimọ ile ẹkọ ti gbọ alaye onun ti awọn ọmọ akẹkọ na se lati ọwọ Olotu ile ẹkọ yi Ogbeni J. A. Oni.

Sugbọn awọn ọmọ akẹko yoku ti nwon lowo ninu otẹ na yio jiya osẹ meji gbako, awon omo akẹko ti yio jiya ose meji na sopaepa wipe, rara ! awon ko tun ni pana sile ẹko na mo ayafi ki nwon gba awon merinlelọgbon ti won le lo pada.

Awon igbimo Alabojuto Ile ẹko na so pe aibamo bi awon ti won fẹ fi iya osẹ meji jẹ won yi ba ko lati pada sile ẹko, ki igbimo ni ipade ni ojo 22nd osu March 1960, lati gbero kini ohun ti oto lati se fun won.

Ohun ti agbo pe oda oro yi silẹ ni pe Olotu ile ẹko na ti sot fin pe ẹnikẹni ko gbodo jade kuro nile ẹko lai gbasẹ, awon kan ditẹ, nwon da ẹsẹ na kọja. Bi oro na ti jẹ nuni.

## POLOWO OJA RE SINU IWE ELETI-OFE L'OSESE


**HINDU SANKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawaches, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Send 4/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 421 Archway Road, London, N.6, England

# E La Eyi Ye Mi

Inu mi yio dun bi olotu bale gba mi laye lati bere qeọ yi. ibere na ni pe, ki ẹgbọn emọ kan gbe iyawo, ki iyawo na sin wa ba aburo okọ tan. Ẹ Jọwọ, o yẹ ki Iyawo na da omọ na pe ni abi ki o ma pe ni orukọ?

Oloto, mo dupẹ lowo rẹ fun aye ti o gba mi. oko ati ada Ijoba koni esyin lẹsẹ o.

Emi ni, Abdul Karimu A Salau




## Okunrin Kan Nwa Oku Ati Oro Kiri

NYASALAND Irohin gbojikan kakiri ilu kan ti nwọn npe ni Mzimba lọlọ kini osu March 1960 wipe Ali anou kan wọ ilu wa o si bere si ṣe ode awọn enia kakiri, ọkunrin kan ti nwọn npe ni Mbamba ti oku na ki mọlẹ, nṣe lo gbe lọ raurau.

Eyi lo fa sababi ti ọkunrin alagbara kan ti nwọn npe ni Oliver Cary fi ḍe lati ... na tabi oro, lati Alijanou na lo lati mu.

Nigbati Oliver de ... igi nla kan leti adagun odo Nyasa ibe lo gbe pagọ si, ... pe ... Oliver bere si gbo ariwo ... awon enia ti o nkegbe ... gbe ibon re ... o si nyọlẹ lo Ori iṣẹ kan ti o ro dede bi nṣe eiye lori igi araba kan.

Oliver ṣakiyesi pe bi ... ba yinbọn lu ile na yio ṣe awọn ti o mbe nibe leṣe, o ... yinbọn kan danu, nigbati oku gburo ibon, o nyara so kale ... wa silẹ, ibe ni Oliver ti ... to ku fun o ... Ọọnlopọ awon ti o ... Alinu na, so pe, ... elem ... so pe ... oku omo Foakins, ... pe o dibi oku Samuel ni Endori.

## ṄJẸ ẸGBA NINA HA TỌ SI ỌMỌ ILE ẸKỌ BI?

Obinrin kan ti o je Igbimọ ti o si tun je Olori awọn oluko la dahun si ibere oke yi pe Mo gbagbọ wipe awọn oluko miran je eniti o nro gidigidi, nko si wipe ki nwọn maṣe ba omode wi bi o ba ṣe. Ṣugbọn ninu ile ẹko temi, emi ko fẹ ki nwọn ma fi ẹgba ba awon ọmọ ile ẹkọ wi, ki a ma fi ẹnu lasan ba wọn wi san. Ọmọ ti nwọn ba mbawi yẹ ki o kọṭọ gba ibawi na, ẹhin na ki o wa fi ẹọ sun.

Lẹhin na ni Ọgbẹni B. E. Esua ti o jẹ akọwe awọn awujẹ Olukọ tun dahun pe, lati ma fi ẹgba ṣe ikilọ fun awọn ọmọ ile ẹkọ alakobere ati awọn ọmọ ile ẹkọ giga nile Nigeria ... pupọ ju ti ilu Oyinbo lo.

Owe kan so bayi pe oluko o ba je ... wa ko ni gbe ... ti o dara ki nw ... wa di ... nkọ awọn ọmọ wa ni e ...

Ninu awọn ile ẹkọ ... agbalagba ni awọn ọmọ ... ibe, iru awọn enia bawonyi ... ki a ma fi enu lasan ...

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos.
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM
"ELETI - OFE, LAGOS
Phone 23370

VOL. XII. No. 556. SATURDAY MAR. 12. — MAR. 18 1960

# Egbe Afenifere Pegede, Nwon Fi Gboro Jeka

Ko si oruko ti a le pe irohin ipinnu ijoba Iwọ orun ti Ọlọla Oloye S. L. Akintọla ti iṣe Olotu ijọba Iwọ-orun (Premier) sọ fun awọn awujọ Oniwe-irohin nilu Ibadan ni ọjọ Monday ose yi ju "Alafia tayọ lọ.

Oloye Akintọla ṣe alaye gẹgẹbi ijọba Iwọ-orun ti ṣ'akiyesi inira ti o wa ninu owoori, owo omi ati owo ina oniman-mọna ti t'ọkunrin t'obinrin nsan ni ipinlẹ Iwọ-orun lati nkan bi ọdun mẹwa sẹhin, ani paapa julọ nilu Abẹokuta ati ilẹ Ijẹbu ti o jẹ wipe awọn obinrin ilu wọnyi ko ni ifọkanbalẹ fun ti owo-ode ti nwọn nfi tulasi-kayandoro san na.

Oloye Akintọla sọ wipe ijọba Iwọ orun ti mura tan lati wa alafia awọn enia ipinlẹ wọn, nipa bẹ awọn obinrin ko ni sanwo ori ati owo ina pẹlu owo omi mọ ni ipinlẹ Iwọ orun ati pe ọkunrin paapa ko ni sanwo ju naira (9d) lọ lori pọnun kọkan titi d'ori ọaiti o ba ri adọta pọnun gba lọdun

Nje eyi ko ha to iro idunnu fun ẹnikẹni lati fi mọ wipe "orukọ ẹni ni iyanu ẹni", orukọ ẹgbẹ Action Group ni ede Yoruba ni ẹgbẹ Afẹn fẹre, oruko na si nhan gedegbe ninu iwa ati ihuwasi awọn opomulero ẹgbẹ na lorekore fun araiye ri.

Bi a ba ni ki a ma ṣe irohin ọrọ Oloye Akintola yi lọ siwaju aye ko ni si fun irohin miran ninu iwe wa nitorina, ko si orukọ ti a le pe irohin na ju "Alafia t'ayọ lọ. Ẹgbẹ afẹnifẹre ti pegede, nwon fi gboro jẹka.




# Onje Ilera Titun Fun Nigeria

## GLAXO ṢE IRANLỌWỌ LATI WO AILERA ỌMỌDE SAN

Onjẹ ilera titun kan ti a npe ni Amama wa ni tita ni Nigeria nisisiyi lati doju ija kọ iku ọmọde ti o pọ ni Nigeria eyi ti aijẹ onjẹ ti o fun ni ilera nfa. Onjẹ yi jẹ iyẹfun papa kan eyi ti a le po mọ onjẹ ọmọde o kun fun ẹpa lilọ ti a ti po mọ iwukara (yeast) wara, iyọ oyinbo ati ọpọlọpọ ohun ti o nmu ilera wa. Ile Ogun Glaxo (Nigeria) Ltd. Ni Apapa ni a ti nṣe Amama.

Ọmọ ọṣẹ mefa titi de ọmọ-ile-iwe ni nwọn saba ma nni arun ẹkunra nitori aijẹ onjẹ atata. Arun ẹkunra jẹ arun ti ifeto wọ ọmọde lara, a ma ni i lara, o si npa ọpọlọpọ. Ti o ba wọ ọmọ lara tan, o ṣoro lati wo nitoripe ki iṣe pe aisan yi yio da ọmọde lamu nikan, ṣugbọn ko ni jẹ ki o nje wu wọn jẹ. Nitori idi pataki meji wọnyi o pataki pe ki a wa ọna bi arun yi ko ṣe ni ba ọmọde ja rara. Bi aisan na ko ba ni ba ọmọde ja, ọmọ na nilati jẹ onjẹ ti yio fun u ni ilera tabi ki a po Amama mọ onjẹ rẹ. (Amama kun fun onja ti o pe). Bi a ba po Amama mọ onjẹ ọmọde nigbagbogbo ko ni jẹ ki arun buburu yi ki o ṣe e.

Awọn Oniṣe-iwosan ni Nigeria ṣe ajumọro nipa aisan yi ninu ipade Onjẹ-iwosan ni Ibadan ni oṣu kẹsan ọdun 1957 nigbati a fihan pe onjẹ ilera, ti iṣe atunraṣe ni kikun, ko si ninu onjẹ ọpọl opọ enia ni ibi isalẹ Nigeria nibiti o jẹ pe ṣu ati gbaguda ni onjẹ wọn pọju. Ni apa ibomiran papa onjẹ ti imu oniruru eya ara ṣiṣe wọn bi o ti tọ sowọn.

Ni 1955 Oniṣegun W.F.J. Cuthbertson, olori iṣe Onjẹ Glaxo ni Greenford, England, nigbati o ṣiṣẹ ni ile-ẹkọ giga (University College) ni Ibadan, ri ọpọlọpọ idamu ti aisi ohun atunraṣe ninu onjẹ nfa wa fun awọn ọmọ Iwọ Orun Afrika. Nigbati o pada si Lond n, on ati awọn oṣiṣẹ rẹ bẹrẹsi wadi onjẹ afikun ti o ntun ara ṣe ti o si nmu ilera ba 'ni ti a le fi ẹpa ṣe pataki rẹ.

Lẹhin ọdun meji, Oniṣegun T.F. Macrae, Ọga Eleto Glaxo lọ ọpọlọpọ irin ajo ni Afrika lati ba awọn Oniṣẹ iwosan ni Afrika ti nṣiṣẹ ni Ile iwosan, Ile ibimo, ilito ati Ile iwadi Ogun soro ati lati gbo alaye wọn nipa aisi onjẹ ilera ati atunraṣe ninu onjẹ. A fi tijetsyo gba a l'alejo ni ibi wonyi ko si le gbagbe iru iba ti awọn oniṣẹ itoju awọn ọmọde ko si Eto Glaxo ti o fun 'ni ni iṣiri pupo.

Amama dara lati fun ọmọde pẹlu onjẹ rẹ ni ekun ṣibi Glaxo mẹrin lojojumọ (1 oz) Pipo mo onje ni titi omo yio fi pe ọdun mefa tabi meje. Glaxo pinnu lati jẹ ki rira rẹ rorun fun awọn ti o fẹ lati ra Amama fun omo won. Pali Amama, ti o kun ṣibi mejilelogbon fun ilo ọjọ mẹjọ, jẹ ṣile kan abo (1s 6d) pere eyi ti olukuluku enia le fi irorun ra.

Lati ko awọn enia ni ilo rẹ ati lati polowo rẹ, ọpọlọpọ mọto ni a gbe fun awọn enia Africa, ti ati ko jafajafa ni ipolowo ọja, ti o nkakiri Nigeria lati mu irohin yi ba gbogbo enia. Tẹlẹtẹlẹ, ni awọn agbegbe wọnyi, awọn enia ti gbọ irohin Amama dunti nitori ni ximoye Ile iwosan ni ati nd n wo ti ati nṣtri pe o dara. Awọn mọto wọnyi lọ kakiri ọpọlọpọ ilu ati ilẹtẹ ti nwon nlo o bi oni ye ki a lo o han awọn enia. Pẹlu gbogbo iwọnyi aṣe Sinima Amama, ti oie pe kiki ara Nigeria ni oṣe, ti afi han awọn enia ni gbogbo ile Sinima ni Nigeria, ati tẹ oniruru iwe akiyesi ni enia ti a lẹ mọ ọja ati ọpọlọpọ ileto.

Lati ọdunmọdun ni aisan ẹkunra ọmọde ti npa ọpọlọp ọmọde pupa larin awọn ti ngbe Ile Yoruba. Pipa ti o npa wọn bayi, idamu ati irora awọn ti o kolu ti ko ṣe fi ẹnu so, mu ki oje olori iṣoro fun awọn Onitoju ọmọde ni Nigeria. Ireti na de nisisiyi, ti awọn alakoso Nigeria ati awọn Oniṣegun ti ntoju ọmọde ti gba, pe aisi onjẹ ilera ati atunraṣe to ninu onjẹ yio da iten nipa ilo "AMAMA" ni Ile Nigeria ati pe nitori idi eyi Nigeria yio tubo sunmo atida ominira ninu ọran iṣowo.

# Itan Bi Hausa Ti Se De Ariwa

(O bere loju ewe keta)

Dajudaju Bayajida wo garawa ati ejo yi gun oke nigbati o wo de ọnu Kanga, o ju okun rẹ silẹ o ki ejo ni orun mole o si nwo bo.

(Iyoku di ose ,ti o mbo)





## GOMINA AGBA ILẸ NIGERIA.



Ẹniti a nwo yi ni Sir John Stuart Macpherson, eni ti o koko je oye Gomina gbogbo-gbo (Governor General) nilẹ Nigeria nigbati akoko re to lo fi ilẹ Nigeria silẹ ki Sir James Robertson to wa gba ipo re

## Olori Awon Alayo Eko



Ọgbẹni ti a nwo ninu aworan yi ni okunrin gbajumo kan ti nwon npe ni J.K. Randle, o ni je omo bibi inu Dr Randle Ologbe ti ile re wa ni opopo Ẹbingbetu. O je okan pataki ninu awon ota muluku ninu ere ayo igba [a/ye re.

**Orun rere.**

## Olorun Ko Gbawa Lowo Jamba Moto.




Ẹwo ọkunrin Ọlomọlanke ti o nkọja lo yi, ko pa ofin oju ona **moto mo, bẹẹ ẹ ni i pe moto mbo,** ko si ya kuro lona.

# Ikede Pataki

A fi wosika wa ọṣẹ yi ke si ẹnyin Ọkawe wa ti o n bẹ ni Oke-okun (Ghana) wipe ki ẹ fi oruko awọn ọrẹ nyin ti o nka iwe irohin ni ede Yoruba ranṣẹ si wa, ki a ba le ṣe eto lati fi iwe irohin Eleti-Ọfẹ ranṣẹ si wọn.

Ẹniti o ba fi oruko enia pataki mejila ranṣẹ si wa ti wọn si sanwo iwe wa silẹ fun ọdun kan ṣaudi a o fi iwe irohin Eleti-Ọfẹ ranṣẹ si olawarẹ fun oṣu mẹfa lọfẹ.

Olotu.

# Itan Ogunbebe Ati Ajantiele

Ogunbebe jẹ obinrin ọmọbibi ilu Ajantiele. O si jẹ iyawo Oluwẹri. Jakuta jẹ orisa ina ti o ti sa gbogbo agbara rẹ ki o ba le gba Ogunbebe kuro lowo Oluwẹri. Nigbati aiṣeṣe gbẹ de, ti Oluwẹri takun re orun, Jakuta ki Ogunbebe molẹ o si gbe lo si Igbẹti. Ajantiele bere si wa umo rẹ kiri ti o to pade awodi ti o se afẹfẹ lu pe Jakuta l'o gbe Ogunbebe lo si Igbẹti ile - Oyo.



AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O.BOX 599. LAGOS.

# Itan Bi Hausa Ti Se De Ariwa

(Lati ọwọ B. A. Carew)

Nigbati Bayajida fi Nagira si ilu Biram o rekọja lọ siwaju pẹlu ẹṣin rẹ lati sa asala fun ẹmi rẹ. Ṣugbọn ilẹ si ṣu ba a ni ilu kan ti a npe ni Daura.

Daura jẹ oruko obinrin, on na si ni ọba ilu na ṣiwaju Daura yi ọpọlọpọ obinrin ni o ti jẹ ọba si ilu yi gẹgẹbi Yakani ti o kọkọ jẹ ọba si ilu na ati awọn Tabwoi, Waizam, Waiwai, Gidirgidir ati Nagari.

Gbogbo awọn ti a ka yi ni nwọn jẹ ọba ninu ilu yi ti a si npe ilu na ni oruko wọn ki o to kan Daura o pọ ninu ilu Ariwa ti awọn obinrin si ti jẹ ọba, ao sọ wọn ti a ba de ibẹ.

Bayajida wọ si ọdọ arugbobinrin kan ti oruko rẹ ma njẹ Ayana, o si gba ni alejo. Nigbati Bayagida sọ kalẹ kuro lori ẹṣin o bere omi mimu fun on ati ẹṣin rẹ.

Arugbobinrin yi sọ fun pe ko si omi nitoripe ọjọ meje meje ni awọn nma pọn omi ni ilu wọn ọjọ na si gbọdọ bọ si Jimọ.

Ni ọjọ na ọwẹ, gbogbo okunrin ilu gbọdọ lọ si ile baba alawo kio si ṣe etutu ti o to ti o si yẹ ki a to le tọ okun bọ inu kanga lati fi fa omi.

Bayajida bere lọwọ iya kini idi rẹ ti e fi jẹ wipe ọjọ meje ni ẹ ma nfa omi ninu ilu yin?

Ayana si da lohun pe Ejo nla kan mbẹ ni kanga ilu wa ti yio pa ẹnikẹni jẹ ti o ba fa omi lai jẹ pe ọjọ pe ki a si ṣe etutu tabi rubọ rẹ.

Ṣugbọn eyi yi jẹ eri n eti Bayajida o si binu gidi gidi dapo ti o fi bere garawa ati okun lọwọ iya na ni ale ni gbogbo akan wọnyi ṣẹlẹ.

Bayajida so okun mọ garawa o si da ori kọ idi kanga o ju garawa si inu kanga lati fa omi nigbati Ejo yi gbọ iro garawo o sure gunke wa o si ki garawa na mọlẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹrin)

# Ewon Osu Mefa Fun Aiko Mo Iwon Ara Re

Awọ ilu ma tẹ, iwọn ara rẹ lo mọ lo da'fa fun alaru ti o kọkọ de ilu Eko ti o fi lo aṣọ ẹwọn.

Nigbati alaru yi wọ lu Eko, o bẹrẹ si gba aru, tọrọ kọbọ. Ni ọjọ kan o ri awọn kan ti nwon ko awọn enia sinu moto ko si mọ pe awọn Ọlọpa inu ni nwọn ṣa awọn ọlọṣa sinu mọto, o ṣe bi nwọn ti ngba awọn osiṣẹ lebira ni.

Alaru yi sunmo wọn o ni "Emi na yio lo pelu". Awọn Otelemuyẹ bere lọwọ rẹ pe o ha wa ninu won bi? o da wọn lohun pe bẹni Nwọn si ni kio wo inu moto o si wo o.

Dereba fi ina si moto, geregan o di ogba ẹwon, o fa igba ta, o ni iṣẹ lebira ni on ṣe bi nwọn gba won lati lọ ṣe. Bayi ni lebira yi fi osu ogba ẹwọn fun alẹ ọjọ kan.

Kere o !

A ti ni oriṣiriṣi egbogi fun arun Inarun ati arun Jedi-jedi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, l'okunrin ati l'obinrin, ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHRES
MEDICINE STORE
7, Egerton Road, Lagos

## ẸWỌN ỌDUN GBERE LO DARA FUN ỌDARAN

Olotu,

Gba mi laye lati kebosi lọba Ijọba wa latari ọrọ awọn arufin ti o tunbọ npọ si ni ilẹ wa yi. Nitoripe gbogbo awọn iwa ti ko dara, ti o si lodi si ofin ti nwọn nhu lode toni lẹhinti ogun pari tan ni awọn aṣa buruku na bẹrẹ. Iru iwa awọn aṣa na ni awọnyi:- Chọmọgbọmọ, Ọlọṣa tabi awọn ti o nlọ dana ati awọn ti o nṣe owo alvaderu. Iwa mẹta nwọnyi buruju ogun Dahomi lọ.

Bi Ijọba'ba nfi ẹwọn ọdun gbọrọ, tabi ẹwọn ọdun gbere, ti ko ni ade mọ tabi wiwa kuro ni ilu dẹruba wọn, a rope awọn arufin ra yio mọwọ kuro ninu iwa buruku pẹlu tulasi nitoripe ko si ẹni ti ofẹ ya pẹlu awọn ẹbi rẹ tabi aya rẹ, ọmọ rẹ, Iya ati Baba rẹ ti ojẹ wipe ki oma ṣe fi oju ri wọn mọ tabi ki omaṣe gbro wọn laijẹ wipe oluwarẹ ti ku.

Nigbati ijọba ba fi awọn enia meji tabi mẹta ṣe apẹrẹ fun awọn ọsọlẹ wọnyi, o daju wipe nwọn o wa ọwọ iwa bubuau bọ ilẹ.

Johnston Johnson Kuyẹ

# Gomina Iwo Orun



Ẹniti a nwo yi ni Ọgbẹni Sir John Rankine Gomina Iwo-orun Ilẹ Nigeria, o lo ṣe ayẹwo ilẹ Bini Laipẹ.

# Mosalasi Jimo Ilu Ajilete Milingindin

Alhaji Najimu-Deen bere wasi itọwọjọ, itore-owo ati owo afinu-fẹdo da fun kiko Mọsalaṣi Jimo ilu Ajilete ni ọjọ kefa oṣu Nov, 1959. Asi berẹ mimọ ile Ọlorun na ni ọjọ kokandin-lọgbọn oṣu Nov, 1959. Nwọn ṣe eyẹ kikan ile na ni pana ni ọjọ kẹtadin-lọgbọn oṣu February, 1960.

Ọpọlọpọ awọn enia l'o wa sibi eyẹ na lati awọn ilu okere; diẹ ninu awọn enia pataki ti o wa sibẹ awọnyi:- Lemọmu Jamiyu, Ilaro ati ọpa ọyẹ rẹ, Alhaji A. S. Adewumi, Ilaro, Lasisi, Seriki Imale Ad[illegible]-Odo, T. A. Alowomaṣe Alufa Akọmọnikewu, Alufa Atiku N[illegible], Alhaji J. Amosa, R. S. G[illegible], A. Sanusi, L. Oreofẹra, R. Ayodeji, Ṣafaru Alaga, Dada Areogun, Baba Ijo, ati Joseph Aladura.

Alhaji Najimu l'o ṣi adura na, gbogbo awọn ọmọ [illegible] Imale Ajilete si ṣe adura [illegible] (Hammer) na, nwọn fi le Lemọmu lọwọ, o si tun fi le Ọgbẹni Abudu Rahaman Adeọṣun, alaga igbimọ kiko Mọsalaṣi na lọwọ, nwọn wa da pada si ọwọ Alhaji Najimu—Deen. Ọwọ Alhaji yi ni a wa[illegible] Mọsalaṣi Jimo ṣe pataki ninu [illegible] ti musulumi bo ti po ni[illegible]. Ẹsin Islam l'o si je pataki ju gbogbo ẹsin lọ. Ẹgbẹrun [illegible] run ati Ọgọrun marun [illegible] ni nwon fi yori kiko Mọsalaṣi na.

Alhaji Najimu si fi ọlu (Hammer) na le Kafinta lọwọ, Ọgbẹni Sanusi Akande, wipe ki o lo bẹrẹ si fi kan ile na, bi Kafinta ti fi kan ile na gba! bẹni agba mẹta dun lẹralera, gbogbo enia si yombo Anobi.

A kirun Jimo akoko ninu Mọsalasi na ni ọjọ kerin oṣu March, 1960. Alufa Atiku Na'bi l'o ṣiwaju kirun fun wa. Alhaji



ALHAJI NAJIMU-DEEN

Najimu Deen si ṣe adura ṣiṣi ni ọjọ na. Alhaji A. Arowoṣafẹ akọwe Igbimọ, Ọgbẹni Abudu Rahaman Adeọṣun ni Alaga igbimọ Mọsalaṣi na.

Ẹ yombo Anobi: Salalau Alehi Wasalamo. Alhamidu lilahi.

# ELETI-OFE D'ARABA




## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajela ọmọdẹ agbọmọla bi orisa, akọkọlakọ ogun ti ndẹmọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti npa otutu rẹ wasawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiku di ikugbegbe, o ṣ'ọmọ ti nhehin l'ore. Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aipẹri ri d'ẹkun iyọnu Olugbala l'ọmọ ti nyagbe ọrin o kapa inu wọ, o fi jẹdi l'alupa gbogbo abiyamọ nyọ ṣe ṣe. Ela ri i o roju, Orere ri i o na'gbẹ bo'ra Ẹyi npa lẹmọ lo dilẹsọ, ọrẹ ikoko, kọjẹmani awọn abiyamọ, ẹni araiye njidu ra. O de ilu Ibo, o doga, a de ilẹ Hausa, o d'ọba, gbogbo o nisegun l'o sọ pe ko lẹgbẹ O ogbo ọmọde lo ufẹ ẹ fun ilera

IGO KEKERE 2/6d NLA 4s owo ọkọ lọtọ.

THE ẸGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2 Ebute -Metta



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ti o wọ ẹwu awon Alhaji Malam Bello Dandago, igbakeji [illegible] ni arin meji ni Ọgbẹni L. W. Bear ti iṣe Oniwe irohin ijoba, ẹnikẹta ni Ọgbẹni D. C. Igwe

Advertisement NO. 26.

# Public Notice

## Public Holidays Ordinance

It is notified for general information that His Excellency the Governor-General has delared that Tuesday, the 29th March, and Wednesday, the 30th March, shall be kept as puplic holidays in celebration of the Moslem festival of Id-el-Fitre, that Thursday, the 21st April, shall be kept as a public holiday in celebration of the Queen's Birthday, that Monday, the 6th June, and Tuesday, the 7th June, shall be kept as public holidays in clebration of the Meslom festival of Id-el-Kabir, and that Monday, the 6th September, shall be kept as a public holiday in celebration of the birthday of the Prophet Muhammed (Id-el-Maulud).

Ministry of Internal Affairs,
Lagos.

# Gomina Agba Soro



Gomina gbogbo gbo soro lori wipe on yio fise sile ni nu october, 1960, ti o jade ninu iwe irohin kan laipe yi, o wipe on ko ni imo nipa re ati pe iwe irohin ni on ti ri. Beni ko si eniti o le so ohun ti yio sele ni osu october.

## OKUNRIN KAN MU OMO ONIGBESE RE DI OWO

ABA Okunrin kan ti o bi om;kunrin kekere kan je ore re ni Poun meji, su. gbon nigbati baba omo na ko ri owo san ti olowo re si nfe owo lati lo, o ki omo onigbese re mole o si gbe lo bamubamu.

Baba omo na lo rohin fun awon olopa awon Osisomuye wa bere si wadi wipe nje okunrin ti baba omo na je nigbese k, lo gbe omo na lo gba lo baun ?

A gbo wipe ol, pa inu ti tuka si ode ti nwon lepa ibiti omode na wa kakiri oro na si mbe ni ikawo awon olopa nwon nse iwadi re lowo.

# Idajo Ejo K. O. pelu ZIK Di Osu To mbo



Nipa ejo ti Ogbeni K-O Mbadiwe pe Zik si kotu gafan ni Eko, wipe ki adajo ba on gba owo egba marun poun lowo Zik nitori ti o so on di eni abuku larin gbogbo enia wipe emi fe pa on.

## Imoran Fun Awon Obi

Nitori okunkun ni eni ti ko mo iwe wa. Eniti ko mo iwe ko ni mo dandaju ohun ti o nlo lode tori ohun ti awon ba so fun u ni o ma a je ohun ti yio mo, yala o tona tabi ko tona. Ni opolopo igba ni awon yio ma a tan ni sohun. Nipa bayi, awon le ba igbesi-aiye re je. Bi o ba ni ohun isura kan, eniti o mo iwe kan ti o si mo ko daradara ti o mba a lo le fi eton gba a lowo re. Idi niyi ti awon obi fi ni lati ko omo won ni iwe.

Eniti o ba ko omo re ni iwe daradara ni o fun omo re na ni imole aiye. Omo na yio mo dudu yato si funfun Enikeni ko ni le tan je Idi kan tun niyi ti e gbodo fi ko omo nyin ni iwe. Omo ti o ba mo iwe daradara yio le sise otata daradaro ju ti eniti ko mo iwe lo. Id miran niyi, Ti e fi gbodo ko omo nyin ni iwe daradara.

"Owo (money) ni oni oro" Nitori obi ti ko ba ni owo lowo dada ko le ko omo re ni owo lowo pupo ti ko si fe lati na a fi ko awon omo re ni iwe. Dipo ki awon nkan wa fun anfani awa omo won, nse ni awon ngba n fun awon ale tabi ki nwon ma a ji ra oti mu Eniti o ba ko omo re ni iwe dada ti o si fun ni eko ile pelu ni o se e ni ore iti bolat.

Emi ni,
Y. Ayinla Disu.

## OKUNRIN KAN SA KURO NI OGBA EWON NITORI IYAWO RE

Odomokunrin kan, Ladipo Ayinde, lo se asemase ti won si fi si ewon osu merindinlogun ni biti on se ewon yi lowo lo ti ri aye sa kuro ni ogba ewon, ki owo awon olopa to te lori ekeji, won si mu esun re lo si waju adajo.

Alatako re so wipe, ninu ewon ni Ayinde wa won si mu lo si ode lo sise, nigbati ori pe dereba won gbe oju sibomiran, beni oyi si koro osi salo

Odaran elewon na so fun adajo wipe, ninu oyun ni iyawo on wa ti on fi wo ewon, on si gbo wipe iyawo on na ti bimo, ibe ni ibanuje wa su bo on loju wipe on nikan ni iya on bi ko si eni ti yio ba obinrin na se itoju omo.

Adajo so wipe anu re se ni lojo, sugbon bio ti wu ki ori, a ko nilati gba iru asa be laye ni torina, ki olo si ewon odun meji, ni jagun batun fi owo gba ori re mu.

## Omiran Titun Tun De

Omiran Alakuku ni a gbo wipe o koko je oye omiran nile Nigeria sugbon nisisiyi Alakuku ti teriba so.

Ki Omiran Alakuku to faiye tile, ni Omiran kan ti nwon ope ni Pawa (Killwe) ti di Agbara killwe po jojo tobe ti oje pe owo kansoso lofi nwon awon enia ni enia p po o mu moto dan, moto na ko si le lo. Nwon fun ni oruko" Superman eyiti a le tunmo si oro yi bayi pe, "Alagbara julo.

Nisisiyi Omiran keta ti tun jade lati ona ile Kontogora, oruko re nje Inorcent Opara o si pinnu lati lo dan agbara re wo lodo killwe Bi Idahomi meji ba foju kan ara won, nigbana ni okunrin foju kan okunrin.

POLOWO OJA RE SINU IWE ELETI-OFE L'OSESE

Printed& Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street, P. O. Box 467 Lagos Phone23